**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**BÍBORÍ ÌWÀ ÌKÀ ÌDÍLÉ**

**OṢÙ KẸTA, ỌDÚN 2025**

Ìwé Mímọ́ Kíkà: Gẹ́nẹ́sísí 4

Ìjẹ́wọ́: Lúkù 10:19

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sí Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ibi gíga àbò àwọn àjẹ́ ìdílé, gba ìparun, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo ìtàkùn àsopọ̀ àwọn àjẹ́ ìbílẹ̀ àti ti òkèrè, túká sí wẹ́wẹ́, ní orúkọ Jésù.
7. Olúwa dìde, mú àwọn ohun-èlò ìjà agbárakágbára tí ó ti fa wàhálà fún mi kúrò, ní orúkọ Jésù.
8. Gbogbo ohùn òkú tó n dásí ọ̀rọ̀ ayé mi, kí agbára Ọlọ́run gé ọ dànù, ní orúkọ Jésù.
9. Mo yọ ọwọ́ ìkà ìdílé kúrò nínú gbogbo ọ̀rọ̀ ayé mi, ní orúkọ Jésù.
10. Ìka Ọlọ́run, ṣí ọkùnrin alágbára ìdílé nídì kúrò nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
11. Mo pàṣẹ wí pé n kò ní jẹ láti inú ekuru nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
12. Olúwa, sún mi kúrò láti òjìjí ìrora bọ́ síbi ògo mi, ní orúkọ Jésù.
13. Gbogbo àlá òṣì tí ìkà ìdílé ṣagbátẹ̀rù rẹ̀, kú, ní orúkọ Jésù.

14. Ìka Ọlọ́run, tú ibi ìfarasin ọkùnrin alágbára ìdílé mi ká, ní orúkọ Jésù.
15. Olúwa, fọ́ gbogbo ilẹ̀kuǹ t'ó kọ̀ láti ṣí fún mi, ní orúkọ Jésù.
16. Gbogbo ètò ibi tí wọ́n ṣètò ní àgọ́ ìkà láti mú ìparun bá mi, Olúwa, tú iná Rẹ jáde láti jẹ wọ́n run, ní orúkọ Jésù.
17. Àrá Ọlọ́run, túká kọjá àtúnṣe, ìpìlẹ̀ àjẹ́ nínú ìdílé mi, ní orúkọ Jésù.
18. Èyí ìyówù nínú àwọn ibùkún mi tí àwọn àjẹ́ ìdílé fí n ṣòwò, padà sọ́dọ̀ mi, ní orúkọ Jésù.
19. Agbárakágbára tí wọ́n ṣì wà síbẹ̀ láti pamírun, òpin yín yóò dé báyìí, ní orúkọ Jésù.
20. Olúwa, jẹ́ kí ẹ̀jẹ̀ Jésù fi èdìdí sórí ayé mi lòdì sí àgọ́ ọ̀tá, ní orúkọ Jésù.
21. Àwọn ejò àti àkekè, tí àjẹ́ olórogún ìgbà-èwe gbìn sínú ayé mi, ẹ kú, ní orúkọ Jésù.
22. Gbogbo ràbọ̀ràbọ̀ ibi ìpìlẹ̀ olórogún lórí ayànmọ́ mi, gba ìfagilé nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
23. Olúwa, jẹ́ kí gbogbo iṣòro olóríkunkun àti àwọn ọ̀tá olóríkunkun mi rí ìfarahàn Rẹ tó n banilẹ́ru, ní orúkọ Jésù.
24. Ohunkóhun tí èṣù gbé lémi lórí láti jí àwọn ibùkún mi, gba iná, jó di éérú, ní orúkọ Jésù.
25. Áísìkí mi tí àjẹ́ olórogún fi sínú ìgbèkùn, gba ìtúsílẹ̀ nípa iná, ní orúkọ Jésù.
26. Gbogbo ọfà àjẹ́ olórogún, tapadà, ní orúkọ Jésù.
27. Iṣòrokíṣòro tí èṣù gbé lémi lọ́wọ́, Ọlọ́run dìde, gba a kúrò lọ́wọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
28. Odi Jẹ́ríkò tó dúró lòdì sí ọ̀nà àbáyọ àti àwọn alàjá mi, wólulẹ̀ báyìí, ní orúkọ Jésù.
29. Agbòrù olórogún tó bo iràwọ̀ mi, kú, ní orúkọ Jésù.
30. Gbogbo ìpadàsẹ́yìn tí àjẹ́ olórogún ṣètò sínú ayé mi, kú, ní orúkọ Jésù.
31. Olúwa, pàṣẹ òpin sí gbogbo iṣòro nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.

32. Gbogbo alàfo òkùnkùn tó n gba ògo àti alàjá mi, gba ìfagilé nípa iná, ní orúkọ Jésù.
33. Gbogbo ègún tí àjẹ́ olórogún fi sórí mi nígbà tí mo wà nínú oyún, fọ́, ní orúkọ Jésù.
34. Mo pàṣẹ kí gbogbo ilẹ̀kùn àti ẹnubodè àwọn anfàní nlánlá ṣí fún mi, ní orúkọ Jésù.
35. Mo pàṣẹ kí ìgbóguntì igbàdégbà nínú ayé mi àti ìdílé mi dópin báyìí, ní orúkọ Jésù.
36. Ìgbóguntì ìsisìyí ìyówù, tó nlọ lọ́wọ́lọ́wọ́ nínú ayé mi, dópin, ní orúkọ Jésù.
37. Gbogbo obìrí ìdádúró ìkà nínú ayé mi, fọ́ báyìí, ní orúkọ Jésù.
38. Ifòróróyàn láti tẹ̀síwájú jákèjádò àgbáyé, bàlé mi, ní orúkọ Jésù.
39. Nígbà tí ohun gbogbo bá kù fẹ̀rẹ̀ kó dára, èmi kò ní di àwátì, ní orúkọ Jésù.
40. Gbogbo ìṣàn òdì láti ipàsẹ̀ àjẹ́ ìdílé tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí mi, ká kúrò báyìí, ní orúkọ Jésù.